# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. II. No. 101. SATURDAY, JUNE 14, 1924. FOURPENCE.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugooni and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu ọ̀wọ̀ Ilẹkẹ, oriṣiriṣi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elẹjo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, aṣọ iṣ'ọṣọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹla (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maṣini *Vesla*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi ọ̀wọ̀ wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ukole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ Iorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## What a wonderful Medicine is this?

IS IT MAGIC?

D. A. Thompson, Licensed Herbalist has just received these from Şaki and Bariba to cure any complaints brought to him viz :—Ikọ fe e, Warapa, Aşiwere, Ọlọ Inu, Pakunpọ, Wodi-wodi, Atoriwa, Jakutẹ, Oju ti o yọ owo. Jẹdi-jẹdi, with assorted medicines suitable for barren women. Children's treatment and assorted Agunmu in bottles in the shop for sale.

*The proof of pudding is in the taste*

**Come and have a trial**

No. 2, AROLOYA STREET, LAGOS.

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**
HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ l dọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, lẹti ile Johnson Agbẹjọro.

# CONGOLEUM SQUARES.

## THE LATEST IN FLOOR COVERINGS.

We have been appointed Sole Agents for Nigeria for CONGOLEUM SQUARES, and can horoughly recommend them on account of their splendid wearing qualities, and also because of the cheapness in price. They are especially suitable for cement floors.

They are easy to keep clean, but hard to wear out, unaffected by dampness, moisture, insects, rot-proof, and strictly sanitary.

We hold a stock in a good range of patterns, and various sizes | from 6 feet by 6 feet, to 15 feet by 9 feet.

*We invite you to come and inspect same at:—*

JOHN WALKDEN & CO. LTD.,
MARINA, LAGOS.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices* : 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

IKẸKẸRẸ NF'ỌRAN IKU Ṣ'ẸRIN.

Ni ọsẹ melo sẹhin, a kilọ fun awọn onisowo gari alahanku-irẹ pe ki nwọn fi ẹdẹ si gbigbọn garı ṣọwọ s'oke okun, ṣugbọn o dabi ẹnipe sibẹsibẹ nwọn ko fẹ mọ: nisisiyi a gbọ pe iwọn gari oni tọrọ ri di nain pẹlu kọbọ kan nisisiyi! eyi ha dara bi? Nigbati awa funraw a ba npe iyan ki o mu, a ko ṣai mọ pe gbogbo wa ni yio kan karikari. Bi ojo ko rọ, bi igbado ko gbo oju gbogbo wa ni yio ja. Ewo tilẹ ni ebi ti a nda pa awọn Majẹsi lọna bayi.

Lẹkan si i, a ke si Ijọba, ki nwọn ma ṣai bojuto ọran ti gari wiwọn yi fun Ilu. Onile nke, Alejo nke pe owo gari fo s'oke sibẹsibẹ a nri awọn ti nwọn nda Agunla Aguntẹtẹ ninu awọn onişowo gari yi.

O yẹ ki nwọn ronu ika ti nwọn nṣe yi nipa did'ebipa enia; gidigidi ko mọ'la. Bi ina ba jo ni jo ọmọ ẹni, ti ara ẹni la kọ gbọn.

Ki a ma d'ebi pa Ilu fun ati ni owo ṣile, ko tọ suna; aiye la b'owo, aiye la o si fi si lọ ! ! !

OKUTỌ, AGBEDE BI OFE A M'ARA RẸ BI ODẸ.

O'a si ni leti fẹnrẹn pe a yan Alagba E. H. Oke ti Ibadan si Ijọ Igbimọ Aṣofin *Nigeria*, ti eyi ba ri bẹ, njẹ a ba Ọgbẹni wa na yọ si ọla ti a da yi: boya pupọ ninu wa ko mọ pe ede *Hebrew* ati *Greek* nke kanran lori Ọgbẹni yi, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti ede Gẹsi ti o yọ lẹnu rẹ mọ: nigbati o si nṣe olukọ ile iwe awọn "Tulẹ" ni Eko nibi ni ọjọ jọjọ s'ẹhin, ṣaṣa ninu awọn ẹgbẹ rẹ lo to rọ sẹhin fun iwe mimọ ni ijinlẹ.

A ba awọn ara wa ni Ibadan yọ si orire wọn yi.

EJI DE, EJI MA DE O BANSA!

Ọsọrọ ojo to balẹ lẹnu ijọ mẹta yi ko ni ṣai ṣe awọn Agbẹ lore, ati pe o si din oru ku ni'lu; lati igbati ojo yi ti nrọ lemọlemọ bayi, a ri awọn ẹlomiran ti nwọn nkun pe nwọn ko gbadun, nitori pẹtẹpẹtẹ ti o sọ ilẹ da, bẹ lori "ojo ṣ'ore gb'epe" gẹgẹ bi owe wa kan; ko si ẹnu ẹda ti ki ndun kara ki o tun ma dun koro; bi oru mu ju a o sọ. bi ojo si rọ ju a o sọ, ṣugbọn loju wa, Ẹlẹda wa mọ ohun ti o tọ fun awa ọmọ Rẹ ki o to ma fun wa ni ojo ati ẹrun lakoko wọn; ojo rirọ si jẹ ọkan ninu awọn ẹbun Ẹlẹda eyiti kosi sisan owo lelori bi owo omi Iju.

Owo-omi sisan yi mu wa ranti ọrọ kan ti a gbọ pe nṣe ni awọn ti Munisipa pe l'ẹjọ owo omi nsa biabia lati gba iwe ipẹjọ; irufẹ sisa bẹ ko yẹ ẹnikẹni, nitoripe niwọn igbati ati nlo awọn omi na, o yẹ o si tọ gidigidi lati san owo rẹ fun iṣẹ atunṣe Ilu. Awọn Ijẹbu ara wa lo ma np'owe pe:— "ohun ti o sunwọn a fu'wo."

Ki ojo ti o nrọ nisinsinyi maṣai jẹ ojo ibukun fun t'olori t'elesi wa.

**Ruby Plates! Ruby Plates!!**
**Ruby Plates!!!**
BOON TO GOLDSMITHS
*Just arrived.*
Call at once and make your choice from :—
DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.
*P.O. Box No. 374.* *Telephone No. 243.*

## [I]WE TI ỌGBẸNI DADA ADESHIGBIN KỌ SI AWỌN IJỌ ỌFFA.

60, APAPA ROAD,
Ebute Metta.
"BAMIDUPẸ" *May 15th 1924.*

"Mo gbọ ohun kan lati Ọrun wa, ti nwi fun mi pe, kọ'we rẹ lati isisiyi lọ, ibukun ni fun awọn oku ti o ku ninu Oluwa; bẹ li Ẹmi nwi; nitori nwọn simi kuro ninu lala wọn."

Si Ijọ Kristi, Ọffa:

Ẹ ku irọju, ẹ ku suru, ẹ ku ọla Baba wa, aimọye adanu ni iku Daddy Randle pa Enia Dudu kakiri gbogbo agbaiye, papa ẹnyin Ijọ Kristi Ọffa to wa labẹ orule yi nisisiyi nipa pipe ti a pe Olukọ nyin lọ si ile, ẹniti a ṣi lọwọ iṣẹ ni *Saturday* ijẹsan lai ṣaisan, ibanujẹ ọpọlọpọ ni eyi mu wa ba awọn ẹbi ati ọmọ rẹ, papa, nigbati a ko gbọ aisan rẹ ti a ba fi sare wa ṣe ọlọjọjọ rẹ, eyi jẹ idahun si ẹbẹ Ologbe igba gbogbo, pe, ki ikọ iku de ba on lẹnu iṣẹ ni ayọ ọkan on, ati pe, ki ọlọjọ on ma damu tabi gbe ẹnikẹni si ipaiya rara.

Pẹlu ẹbẹ ọpọlọpọ ni Ologbe fi tọrọ ati ṣiṣẹ yi, nigbati o wa ba mi sọ, mo sọ fun u pe agba de ko si yẹ ko jina sọdọ awọn ọmọ rẹ, pẹlu omi loju lo fi sọ fun mi pe, awọn ọmọ on ni Ijọ Enia Ọlọrun, ni oṣu *November 1919*, Ologbe ba mi lati Eko de Ẹdẹ, Ire ani Ọffa lati wa wo ibiti o le dara fun on lati ṣiṣẹ, o si yan Ọffa ni ibi ijoko rẹ, a si pada bọ si Eko, gẹgẹ bi ọjọ ori rẹ, ko dun mọ mi lati fun u ni aye ati lọ ṣiṣẹ ni Ọffa nitori jijina ibẹ, ṣugbọn iyọnu rẹ pọ to bẹ gẹ, ti o fi mu mi pinu pe bi o ba fẹ lọ si Ọffa, lọ gba aṣẹ wa lọdọ awọn ọmọ rẹ, nigbati a si ti ṣe itọju jijẹ ati mimu tan, o lọ sọ fun ọmọ rẹ agba (Mrs. Bọjẹ: Adebiyi, ẹniti o ti ṣiwaju rẹ lọ sọdọ Ọlọrun, ki ibusun rẹ ni itura) pe on nlọ ṣiṣẹ Ọlọrun ni Ọffa, lẹhin ti ọmọ rẹ ti fi ẹtan gba owo lọwọ rẹ tan, o wa sọ fun u pe, ẹnyin ki yio lọ si ibikan rara, nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, Daddy wa sọdọ mi, o ni, on nlọ ṣe eṣu sọrun ọmọ on ti ko fẹ ki on lọ ṣe iṣẹ Olodumare, mo be lọpọlọpọ ko mu suru, lọgan Ologbe fi mi silẹ lọ tara sọdọ ọmọ rẹ, ko dẹ iti to wakati kan lo yọ si mi pe on ti gba owo on lọwọ rẹ, ki ntẹ okun si Ọffa, ki nwọn wa pade on lowurọ, *Tuesday 17th June 1920* ni Ologbe wọkọ Kano o si gunlẹ si Ọffa loru ọjọ na, o ba gbogbo awọn Ijọ ti nwọn nduro de e ni *Station*, nigbana awọn enia to ku ni *Church* ko ju 26 lọ, bẹni Ologbe bẹrẹ si iṣẹ rẹ pẹlu gbogbo ipa ti Ọlọrun fun u o si ri ọpọlọpọ iranlọwọ gba lati oke wa; Ijọ si ndagba lojojumọ, itunu ọpọlọpọ ni eyi jẹ fun mi, nigbati mo ka ninu iwe ti o kọ si mi pe o ju ẹgbẹrun enia lọ ti o wa fi ọwọ igbẹhin wọn juba fun oku Daddy Randle nigbati a nsin oku rẹ, dajudaju ni eyi fihan iru ipo ti Ologbe wa lọdọ gbogbo enia Ọffa ati ọwọ ti o fara han lọjọ isinku rẹ, koriko (ekan) ni Ologbe ba lorule *Church*, o si fi silẹ pẹlu orule Panu eyiti ẹ wa labẹ rẹ nisisiyi, nko le kọ sinu iwe ọpọlọpọ iṣẹ ti o ṣe debi pe awọn ara Ọffa nkọrin bi ẹnipe nwọn ni atẹduru ti o nkọ wọn ni onirunru orin, eyiti ẹnyin papa yio jẹri si loni yi, niwọn igbati *Church* yi ba wa lori ilẹ, niwọn igbati ara Ọffa ba wọ *Church* yi, ti nwọn ba si gbe oju soke inu ile yi, ni orukọ Ologbe yi yio wa ni iranti, nigbakugba ti a o ba ṣe itan Ijọ Enia Dudu, orukọ Daddy Randle yio wa ni iranti titilai bi oṣiṣẹ kini ti Ijọ Kristi Ọffa, Panu yi duro bi okuta iyebiye ti a fi sami iṣẹ rẹ larin Ijọ Ọffa.

Ẹnyin Ọmọ-ẹgbẹ Ifẹ, ẹ sọkun lori sare Olukọ nyin, fun lala rẹ igbagbogbo lori nyin lọsan ati loru, ẹnyin Igbimọ *Church* Kristi, Ọfa, ẹ sọkun lori Sarê *Chairman* nyin fun wahala rẹ lori Ijọ yi, ẹnyin ọmọkunrin Ijọ, ẹ sọkun lori sare Olukọ nyin fun ibagbe rẹ, iṣẹ rẹ, lala rẹ, ẹkọ rẹ, lati ọdun mẹrin yi wa ti o ti mu nyin rin ọna ati ri Ojurere Ọlọrun, ẹnyin Ijọ C.M.S ati Baptist Ọffa, ẹ sọkun lori Sarê Daddy Randle, ẹniti o fi ifẹ ọpọlọpọ fa nyin mọra, Ọba, Ijoye, ara ilu Ọffa, ẹ sọkun lori boji Randle nitori ẹ ki yio tun gbọ ohun ifẹ didun rẹ mọ, bẹni ki yio si tun rin ni igboro Ọffa mọ, ẹnyin otutu ati oworẹ Ọffa, ẹ sọkun lori iboji Daddy Randle nitori ẹ ko tun le ṣe nkankan lara rẹ mọ, o daju gbangba pe a o fi aiye silẹ lọ ni ihoho gẹgẹ bi a ti wọ inu rẹ, ẹ jẹ k'a ma tọrọ k'a si ma bẹbẹ pe ki a le ṣe atunṣe ibiti ẹṣẹ ti mu ni ṣẹ ki onikọ to yọ si wa, ti a o si pada ni ihoho lọ ba awọn ẹni rere wa to ti ṣiwaju lọ si ibugbe ọrun, nibi ti ẹni buburu ye yọnu, ti alârẹ si simi. Daddy wa wa nisisiyi ni ilu ti ayọ rẹ ko lopin, ko si ẹni le mọ bi ayọ ibẹ ti dun to, bẹni ayọ ibẹ koi ti la s'ọkan ọmọ enia, ilu ailẹṣẹ ti ko si iku, nibiti nwọn ko mọ ohun ti njẹ odigboṣe, o wa pẹlu awọn ara rẹ to ti lọ ṣaju rẹ, Aya, awọn Ọmọ, Ọrẹ, awọn Ojulumọ rẹ, Iya ati Baba rẹ, nwọn nkọrin ayọ titi aiye ailopin, nwọn nyin Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ, kini ayọ na yio ti dun to, lala alagbaṣe ti pari, ọjọ ogun si ti dopin ko si ebi npa mi nibẹ, ko si orugbẹ ngbẹ mi nibẹ, aniyan owo ati ọmọ nwọn ko mọ nibẹ, otutu nmu mi ko si nibẹ, gbogbo ọjọ lo dara, ogo Jesu si ni imọlẹ ibẹ, o dabi ẹnipe mo gbohun Ologbe ti o nwi seti mi pe "mo ti sare ije mi tan, ija pari, mo ti gba Ade Ogo pẹlu itanṣan imọlẹ rẹ irawọ ainiye, ẹlẹri mi ti ṣiwaju mi de oke, a ṣi iwe iṣẹ ti mo ṣe ni Ọffa paya niwaju Onidajọ ododo, ma bọ ọmọ ọdọ rere, wa bọ sibi ayọ Oluwa rẹ, Ọlọrun alanu, jọwọ, jẹ ki eyi jẹ ipin olukuku wa nigbati a ba de ọdọ Rẹ, ka si le dapọ mọ awọn ẹni ti isalu ọrun nigbati akoko wa ba de.

Ẹ tujuka ẹnyin ẹbi ati Ọmọ oku, ẹ tujuka ẹnyin Ijọ Kristi Ọffa, ẹ ma jẹ k'a ba inu jẹ bi awọn alainireti, iranṣẹ Ọlọrun ti simi kuro ninu lala rẹ, o si ti bọ sinu ayọ Oluwa rẹ, o simi lọdọ Olugbala, isimi titi aiye, o dawurọ la le ki Olukọ wa, sun're, ara, sun're.

Mo gbọ ohun kan lati Ọrun wa, ti nwi fun mi pe, kọwe rẹ, lati isisiyi lọ, ibukun ni fun awọn oku ti o ku ninu Oluwa, bẹ ni Ẹmi nwi, nitori nwọn simi kuro ninu lala wọn.

Ọlọrun sin awọn oniṣẹ rẹ, o si mba iṣẹ rẹ lọ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
DADA ADESHIGBIN.

---

Si Oniwe-irohin "Eko Akete"

Mo bẹrẹ foji,

Inu mi yio dun bi o ba le fi iwe irohin kekere yi si apakan iwe rẹ.

A ri ka ninu *Eko Akete* ti o jade ni ijọ 31 oṣu to kọja, nipa ti ere ti awọn Ẹgbẹ Igbimọ Agbadarigi pe awọn Bọkini diẹ lati jhin yi fun, ni ọjọ *Empire Day* to kọja yi. A si dupẹ lọwọ awọn ọmọluwabi ti o ṣẹ ara wọn lati lọ fun ariya na.

O yẹ Egun gbogbo ko le ni loko ṣugbọn ko yẹ Pakọkọ: ewo ni ti oloraye *Akebioro* ninu rẹ ti o nsọ ọrọ iya ko jọ Baba ti o fi ẹtẹ silẹ to npa lapalapa: bi on ba jẹ to ba mu to ba yo tan, ki o lọ wa ibikan sun si. Ẹ ba wa bere lọwọ rẹ bi o mọ ibiti owo ti wọn fi pe ariya fun wọn ti wa? Bẹ itakun to sagbe lo selegede, awọn to ni owo onjẹ ati ọt' ti iwọ mu lo bi ọmọ ibilẹ ti iwọ tanu lọ ba wọn, gidipa ki ntilẹ wi fun ọ, ṣe Ẹbun Adeniji yi nṣiṣẹ owo rẹ nibẹ ni? Tabi ewo ni ti ẹiọ ọmọ ibilẹ ran lọwọ nwọn ko ran lọwọ bi on ba fẹ iranlọwọ ẹjọ Oyinbo rẹ niyen, a ki fi ẹjọ iku sun lẹsẹ arun. Bi o ba ṣe pe Adeniji ti iwọ nsọkun rẹ yi ni o bẹ ọ ni'ṣẹ si wa; jọwọ sọ fun ki o maṣe taka akọwe Ọba si wa mọ, nitori awa na papa lọ si Ṣukuru oni kọbọ kan ri. Bi o ba ma pe Enia Dudu ni on iṣe ti o si da ara rẹ pọ mọ wa gẹgẹ bi ọmọ iya kanna; awa na yio si dide pẹlu gẹgẹ bi ọmọ ibilẹ lati ṣe ohun ti o tọ si wa ninu ohun ti o kangun si Ijọba labẹ ẹno gbogbo aiye njẹ anfani rẹ loni.

Nipa ti ọrọ ijo ti Ọgbẹni yi tun f'ẹnu-awa ki iṣe kokoro bẹni awa ko gbadura fun idagbasoke ijo-onijo *( Ball Dance )* ni ilu wa. Ha! ọmọkunrin yi mu mi ranti orin kan ti Ologbe Olukọni Mokuolu kọ wa ni Ṣukuru St. Thomas ti o wi bayi pe :—

Mo fẹ ilẹ ti a bi mi ju gbogbo ilẹ aiye lọ bi ko til'ẹ ni ibukun b'oriṣa ni nwọn nsọ nibẹ.

Ti nwọn ko si mọ Ọlọrun wọn, ṣugbọn wọn nkọ wa nihin pe Ọlọrun ni ka sin abuni njẹ abuni, afinihan njẹ afinihan ewe ni ti afari-korodo ni ẹ ṣi wa sibẹsibẹ a ha le pe ni wa jẹun tan ki a si ma yaju si wa eyi ṣe kilibọ o, Akebioro ma dẹ sọ wer-were mọ; nitori owuyẹ l'ọrọ ọrọ ṣoro sọ ọrọ lo pa ẹnikan lana.

Emi ni tiyin nitotọ,
ỌMỌ-IBILẸ.

---

## AKANṢE TITUN.

IRIN DIAMOND ẸLẸMU.

Kere o! Kere o!!

A fẹ sọ fun ẹnyin ara ilu pe a ṣẹṣẹ ni Irin titun Ẹlẹmu ti o npọn ọbẹ daradara, o si wulo pupọ fun awọn Agbẹ; Irin Ẹlẹfufu ni a fi ṣe, o si npọn Ọbẹ, ati Ake bi da-nga: t'ewe t'agba lo nyọ mọ irin yi ṣẹṣẹ, a si ti nlo ni ilu Lome.

Awa nikan ni a ṣe Irin *Diamond* yi fun, awa nikan lo si nta a ni *Nigeria.*

Ṣile kọkan pere ni, a o din ẹniti o ba fẹ ra pupọ li owo. Ẹ wa ke si wa.

**N. V. Handelmattschappij V.H.**
Oyinbo J. F. SICK.
Ọba Ilẹkẹ
ni 5, Ibode lailai,
Eko.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JUNE 14 1924.

## ONI LEMỌMU LO DE!

Kosibotiri ni oye Lemọmu Aguda ti a fi Alufa Mọmọdu Lawani jẹ lọjọ *Sunday* to kọja; awọn enia ti o nwọ nibẹ ko niye nọlupẹlu nigbati o jẹ pe o ni ọwọ awọn Ilu ninu: l'ọtun l'osi ni ariwo sọ lala fun ẹyẹ ati eto ọjọ na tobẹ ti o fi jẹ pe gbogbo rẹ fi lọ dede. Nisisiyi ti awọn Imale Imaro ni Lemọmu tiwọn, yio jẹ ohun ti o r'ọrun nigbagbogbo lati jẹ ki awọn Musulumi na ma wa ni iṣọkan fun ilọsiwaju isin wọn ati fun igbakugba ti Ilu ba ranṣẹ si wọn nipa ọrọ ti o ba kan.

A gbọ pe Mọsalaṣi mẹrin ni ti awọn Musulumi Imaro yi, ti nwọn si dara wọn pọ mọ ti Ilu, a ba nwọn yọ si eyi, a si tun ba nwọn yọ ẹwẹ si kokari ti nwọn muṣe lati gbanujọ pọ yan Alufa Mọmọdu Lawani na si irufẹ ipo pataki bayi larin wọn: eyi fihan gbangba pe lọwọ ọpọ enia ni a le mọ bi ifẹ ba wa fun dida ẹnikan lọla larin wọn, ibaṣe ninu iṣẹ ti o jẹmọ ti Onigbagbọ tabi ti awọn Musulumi bi iru eyi.

A si tun dupẹ pe oju ọjọ dara l'ọjọ yi, eyi si fun olukuluku l'aye lati "sáwù" fun lilọ wo iran oye na. A yin Lemọmu Ratibi titun yi, adura wa si ni pe ki oye na maṣai mọ lori!

ANỌBI NI O LA WA, MALAIRA!

KO MA SI'RU ANABI O, MALAIRA!!

ANABI KARIỌLA MALAIRA!!!

Ni owurọ ọjọ ọsẹ to kọja ni ọjọ kẹjọ oṣu June 1924 ni a fi Mohammed Lawal ti Ita *Glover* ni Eko jẹ oye Lemọmu fun gbogbo awọn Aguda to wa ni Popo Imaro. Ni ọjọ oṣu yi, ẹṣẹ gbogbo awọn Agbagba ni ilu fẹrẹ pe tan ti awọn Aguda pe lati wa jẹri Oye na; ile kun ọna ko -b'ero; orukọ diẹ ninu awọn agb... ...wa ...iwọnyi, Lemọmu agba Lig... Seriki Musulumi, Mọgaji Animashaun, Lemọmu Abasi, Alhaji Sanni Giwa, Adamu Animashaun, Ailara Giwa, Olori Ọmọkewu, Alufa Mustafa, Alfa Amusa Senu Din, Alhaji Okunnu, Lemọmu Alkoran, Snnmọnu Arole, Alli Ọtun, Lemọmu Belo Bashọrun, Aruna Onida, Brimah Ramos, Saka Ramos, Brimah M. Dyson, Lawani A. Johnson ati ọpọlọpọ miran ninu awọn Kiriyo bi Ọgbẹni Britoe A. Salvador, Ọgbẹni Inspector Ries ati Iyasuna Mọṣalaṣi Olosun ati awọn Janma rẹ l'obinrin pe biba nwọn fẹrẹ to ẹdẹgbẹta enia, nigbati ẹsẹ pe tan ni awọn agba Imaro mẹta dide lati sọrọ; Lemọmu Belo Bashọrun ikan ninu awọn wọnyi, ẹnikeji ni Aruna Onida, ikẹta ni Kadiri Ologun, nwọn si sọ wipe awọn ni Janma ran niṣẹ lati sọ fun Lemọmu agba pe ki o sọ fun gbogbo Lemọmu Ratibi pe awọn fẹ fi Mọmọdu Lawani jẹ Oye Lemọmu ni oni, awa lo si ranṣẹ si wọn lati wa ṣe ẹlẹri Oye na fun wa, nwọn ni ẹnyin ọmọ Imaro to wa nihin yi, a fẹ bere lọwọ nyin lọju gbogbo enia, ẹnyin lo ran wa niṣẹ na tabi ẹnyin kọ? Gbogbo wọn ni awọn ni, awọn ni, nwọn tun bi wọn pe, ẹ fẹ ki Mọmọdu Lawani jẹ Oye na tabi ẹ ko fẹ? Gbogbo wọn dahun pe, awọn fẹ ki o jẹ Oye na pẹlu ariwo ayọ nla ni ọjọ na. Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Vintura ẹniti o jẹ ọkan pataki ninu awọn agba Imaro wa dide, o tọrọ gafara lọwọ gbogbo Janma. O si sọrọ to dun mọ gbogbo enia ti o wa nibẹ, o si sọ pe inu on dun pupọ lati fi Mọmọdu Lawani jẹ Lemọmu; ati pe Mọmọdu Lawani yi ni oye na tọsi! nitoripe wahala rẹ pọ ninu Mọṣalaṣi yi, o si mọ rafanda kewu ohun rẹ si dun pupọ nigbati a ba nkirun, lẹhinna ni Mọmọdu Lawani fi ọwọ sinu iwe ofin ti awọn Janma rẹ ṣe fun, gbogbo ofin na jẹ mẹwa, awọn marun ninu awọn Janma Mọṣalaṣi na si fi ọwọ si iwe ofin na pẹlu; lẹhinna ni nwọn we ni Lawani.

Awọn Onimọdiu nfi mọdiu dabira ni ọjọ na nigbana ni a wa ba Lemọmu Aguda de ile rẹ ni Ita *Glover* pẹlu ọpọlọpọ enia l'okunrin ati l'obinrin, nigbati o de ile rẹ, onjẹ pọ bi wọbu a jẹ su ni, fun ẹni ti o wa nibẹ lọjọ na, bẹni tirẹ ri Lemọmu Aguda arowo ṣe fuja. Oye yi a mọ ẹ lori Amin, gbogbo ẹnyin Imaro Aguda mo gbadun nyin o, Oye na ro toto ni ọjọ na, gbogbo ẹniti o wa sibẹ ni o gbadun nyin pẹlu. Mo ki gbogbo ẹnyin agba Mọṣalaṣi na ẹ ku inawo, ẹ ku aṣeyẹ, ẹ ku iṣẹ adini. Allah ko gba gbogbo iṣẹ ti ẹ ṣe ni rere, ko si bukun owo nyin Amin. Mo ki gbogbo ẹnyin ti ẹ wa jẹri Oye na ẹ ku iṣẹ adini Allah ko gba iṣẹ nyin ti ẹ ṣe ni rere Amin, ẹnyin agba Aguda ti o wa ninu Mọṣalaṣi yi ẹ ranti pe ofin wa fun nyin o si wa fun Lemọmu pẹlu.

TAWAKALITU.

## *DEMOCRATIC PARTY*
## Ẹ KU ỌDUN!

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji!

Ni idayi ẹṣi ni awọn baba nla-nla, Ọlọla J. Egerton Shyngle, Herbert Macauley, T. Horatio Jackson ati J. Bagan Benjamin da Ẹgbẹ "Dẹmọ" tabi THE NIGERIAN NATIONAL DEMOCRATIC PARTY silẹ ni Eko, fun ire Ilu wa ati anfani awọn enia inu rẹ.

Ko si ohunkohun ti o rọrun li Eko ju ati da Ẹgbẹ silẹ lọ, bẹni ko si si ohun ti o ṣoro ni ilẹ yi ju ati ri enia atata si Ẹgbẹ na; eyiti o si jẹ olubori iṣoro nibẹ ni ati le ma ri awọn ọmọ Ẹgbẹ yi ni igbakigba ti a ba ṣe ipade Ẹgbẹ.

Iṣoro wiwa si Ẹgbẹ bayi le fi ara sin diẹ li arin awọn Ẹgbẹ ti alakoso rẹ nṣe ariya nkan mimu ati jijẹ nigbagbogbo fun awọn abẹyọ tabi ọmọ-ogun rẹ, ṣugbọn ọjọ ti ilẹ ba gbẹ diẹ fun Baba Ẹgbẹ, ti oda owo da a, ti ko si irẹsi, ti ko si ẹja Kuta olodo, ti ọti Beer, Gin, ati Whisky ko si ni ipade Ẹgbẹ meji lera-lera; ifasẹhin nla yio de, ẹnikẹni ki yio si bikita lati kọja ni ita ile Ẹgbẹ de ibiti o ma lọ si ipade rẹ.

Gbogbo Ẹgbẹ ti o mbẹ ni ilẹ yi loni, lati Ẹgbẹ Alaṣiko titi de Ẹgbẹ "People's Union" ti awọn Dokita Randle nṣe ni Ilupesi, "Dẹmọ" tabi THE NIGERIAN NATIONAL DEMOCRATIC PARTTY ni baba gbogbo wọn; ki a ma ṣẹṣẹ sọ eyiti Archdeacon Ogunbiyi loyun rẹ sinu nisisiyi, ti o si ngbero ati fun ni orukọ "CARR'S CABINET" nigbati o ba bi i tan, yala si ọgba Ṣọṣi Breadfruit tabi ẹhinkule Ọgbẹni Henry Carr papa, iyẹn ti nwọn ko ba de oyun na mọ Archdeacon Ogunbiyi ninu.

Ko si Aṣipa tabi Agbọti ninu Ẹgbẹ "Dẹmọ," ko si alase ti o nse onjẹ adidun nibẹ; sibẹsibẹ, igbagbogbo ni ipade rẹ nkun ṣọṣọ fun enia atata. Ẹgbẹ ti Oloye Oluwa, Eletu Odibo, Olorogun, Aṣọgbọn, Suẹnu, Shyngle, Moore, Jones, Ẹgbẹ ti Afa Ṣọṣi, awọn Ratibi, Balogun, ti ogunlọgọ bọkini Kiriyo, Lọya, Dokita, Sọfiọ, Oniwe-irohin, Oniṣowo, Onigbaujo, Akọwe, ti ọpọlọpọ ọmọluwabi Imale, Ẹgbẹ ti Erelu ati awọn Iya wa miran wa ninu rẹ; ani Ẹgbẹ ti ọmọ rẹ fẹrẹ to ẹgbaji enia (about 4,000 members) kuro ni ṣireṣire Ẹgbẹ. Ẹgbẹ Ilu pataki ni.

Ẹniti o ba wipe on ni ọgbọn pupọ, yio ri ti ẹniti o ju tirẹ lo ninu Ẹgbẹ DEMOCRATIC PARTY, ẹniti o ba si lẹ fọnga iwe-mimọ, kekere ni yio pa ina rẹ nibẹ—Wallahi Tallahi. Ẹniti o ba fẹ taka owo, yio bo ilẹ pirapira; ẹniti o ba fẹ ṣe fari ọmọ, abiamọ pọ nibẹ to wọbu, ẹniti o ba si nṣe igberaga wipe on jẹ enia gigun, yio ba Agamagọ nibẹ; bi o si nṣe fari enia kukuru, a o sọ fun u wipe ki o duro ti Egun nla ti o nfọhun bi enia—Akuruyẹgbẹ inu "Dẹmo," ki a wo ẹniti o ga ju ẹnikan lọ ninu awọn mejeji.

Ṣugbọn, ẹniti o ba nfẹ ọlọtẹ enia ti o korira ilu rẹ, ẹniti o ba nfẹ a-gbe-ni-gbun-ọba, ki o wa iru ẹni bawọnni lọ si iwaju.

Li akoko ti a yan Aṣoju enia mẹta si Igbimọ Munisipa li ọdun ti o kọja, oyun Ẹgbẹ DEMOCRATIC wa ni inu nigbana. Ṣugbọn ọsẹ keji lẹhin na, ni a bi ọmọ titun na; ọmọ arijo, ọmọ ariyọ.

Ẹlomiran ro wipe abiku ọmọ ni; ati wipe ẹmi rẹ ko tilẹ le gun to ọjọ mẹjọ ti a o ko o jade ki a to kan Posi fun u; ati wipe, bi o tilẹ dagba to ati ko jade, a ki yio le sami fun u, nitori ko nṣe ọmọ Alarede.

Ṣugbọn loni nkọ? A ti ko Ẹgbẹ DEMOCRATIC PARTY jade, a ti sami fun u, a ti fun u ni orukọ Suna, a ti ṣe Kọnfameṣọn (Confirmation) fun u, a ti gbe Arede fun u, a ti so Yigi fun u lẹhin Wolimọ. Akọbi ọmọ rẹ, ibẹta tabi ẹta-oko li o fi bi; o bi Lọya meji, Dokita kan. SHYNGLE, MOORE ati JONES; awọn mẹtẹta ọmọloju Gomina, awọn mẹtẹta ọrẹ Ọlọla Donald Cameron, awọn mẹtẹta Aṣoju Ilu.

Inira ti Ogun ajakaiye da silẹ ko kere, awọn Oyinbo kanna ti o wipe nwọn ndabo bo wa nitori ki a le fi opin si Ogun ati Ọtẹ larin wa, li o tun pada di ẹniti o nyin ara wọn ni ibọn fun odidi ọdun mẹrin pẹlu abọ gbako; awọn Oyinbo kanna ti o fun wa ni Bibeli ati Iwe-orin lati ma gbadura fun ohunkohun ti a ba nfẹ, nitori adura ni Ẹbọ Onigbagbọ, awọn Oyinbo kanna ti o nwasu fun wa wipe ki a ma tọrọ aforiji fun ọta wa, ki a ma gbadura fun wọn, awọn Oyinbo kanna li o nfi ojojumọ kan Ọkọ-ogun, li o nfi ojojumọ ṣe Agba ati Ẹtu-ibọn, li o si nsan owo iyebiye fun awọn Ọmọ-ogun (Soldier) wọn ti o wa li oke ati li oju omi bi ẹni wipe "Baba wa ti nbẹ li ọrun, ọwọ li orukọ Rẹ" ko si ninu Iwe-adura tiwọn.

Lati igbati awọn Aṣoju wa mẹtẹta ti de Igbimọ Legislative Council ni nwọn ti nsa gbogbo ipa wọn fun ilọsiwaju Ilu, ti ẹlẹgan li o ku. Nitotọ, ode le; sibẹsibẹ, iṣẹ ko si, owó ko si, òwo ko si: ṣugbọn a ni lati ranti wipe, bi o ti wu ki Kọntraktọ (Contractor) kan le yara kọ ile to, o ṣoro ki o to le fi oṣu kan tabi oṣu meji pere tun ile pẹtẹsi nla ti ina ti fẹrẹ jo lu'lẹ patapata kọ tan. Bẹ gẹgẹ ni ibajẹ ti Ogun ajakaiye ṣe ko le tete tan ni ilẹ, diẹ diẹ ni.

Ni ipade ajọdun pataki ti ọsan yi, ni ile Afari-Ogun (Glover Memorial Hall,) a nreti gbogbo ọmọ Ẹgbẹ DEMOCRATIC PARTY nibẹ, lati wa gbọ rafanda ọrọ, ati lati wa damuso fun Baba-ẹgbẹ ati awọn Isangbe rẹ. A dupẹ lọwọ gbogbo awọn Ẹgbẹ adugbo tabi ẹya DEMOCRATIC PARTY ti nwọn

nșe ipade li arin ara wọn li ọsọsẹ. Irohin ti a ngbọ nipa akikanju awọn ara Ita Balogun, ara Ọlowogbowo, Oke Popo, Oke Itẹ, Isalẹ Eko ati ibomiran; ati ti awọn ti o nṣe ipade tiwọn ni Mọṣalaṣi Alufayati, li abẹ akoso Lemọmu Amọdẹ dun mọ wa ninu lọpọlọpọ. Nitorina, ẹniti ko ba iti wọ Ẹgbẹ DEMOCRATIC PARTY, ijafara l'ewu.

Ọlọla J. EGERTON SHYNGLE, ERIC O. MOORE ati ADENIYI JONES, ẹ ku iṣẹ o. Gunnugun ko nku li ewe, dandan, ẹ ka ṣai di arugbo, dandan. Mo gbe oju wo ọwọ mi ọtun, mo ri igba ogun, mo gbe oju wo ọwọ mi osi, mo ri igba ogun; mo gbe oju wo iwaju mi orere, mo ri igba alagẹmọ ti o gbe ojiji Eko le 'ri rẹṣẹrẹṣẹ; Iku, arun, wahala, rogbodian, oṣo tabi ajẹ ti o ba ni on ma ri ẹnikẹni ninu Ẹgbẹ DEMOCRATIC PARTY, bombata yio bo o mọlẹ fun wa, bombata. Ani, nipa ifẹ Olugbala, ki yio si nkan.

HERBERT MACAULEY, Eko di ọwọ nyin o.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

Ninu Iwe-irohin rẹ ti January 19, 1924, mo bere lọwọ rẹ pẹlu gafara lati mọ tani oluwa rẹ na ti o pe ara rẹ ni *Akede Otitọ* (ti emi *Alọma vi* mọ ni *Akede Aiṣotọ*) tabi ki o tilẹ sọ bi nwọn bi on ni ilu Ajido ni gẹgẹ bi nwọn ti bi emi "Alọma vi" nibẹ ni tabi nwọn ra a wa sibẹ ni, tabi o wa gẹgẹ bi alejo si Ajido, bi ko ba si le dahun njẹ ki o ko igba sile, ki nma ba wa ogunna ọrọ gbigbona le e lori, ṣugbọn ko fi esi kan si gbogbo ibere ọlọgbọn wọnyi, o si tun bẹrẹ lati ma purọ ohun ti ko mọ nipa itan ija Ijọ *C.M.S.* Ajido, lẹhin ti mo ti da a ni imọran pe ki o lọ sọdọ iya Ajẹ ti Endori (*The Witch at Endor*) ki o ba a ji awọn oku rẹ dide ki o si gbọ otitọ ọrọ yi lẹnu nwọn, ki o ma ba kede eke fun gbogbo ilu, mo si ro pe boya awọn oku tirẹ papa kọ ni Iya Ajẹ ji dide fun u lẹhin ti o fi odidi oṣu marun wa Iya Ajẹ na kiri ninu ilu Endori, nitorina ni a ko si ṣe ri otitọ kan ninu ọrọ itan ti o pa silẹ bikoṣe "Aroye ọtẹ."

Owe wa ti o sọ wipe "Bi era (*ant*) ba gun ni bi a ko ba mu u kuro yio ṣebi igi ni on ngun" li o jẹki nfẹ sọ ọrọ diẹ fun *Akede Aiṣotọ* yi, lati tubọ pa lẹnu mọ.

Emi ko ni *Akede Aiṣotọ* yi ti mo ti fi Oguna ọrọ diẹ pa lẹnu mọ, ki o maṣe rohin iṣẹ rere ti awọn Olutọju Ijọ C.M.S. Ajido ba bẹrẹ si ṣe si ilu t'emi nisisiyi, nitori ilọsiwaju ilu yi ninu isin Ọlọrun ati ilaju si ohun ti iṣe rere labẹ asia Gẹsi ni ohun ẹdun ọkan emi "Alọma vi" ṣugbọn nigbati o ti jẹ pe ọrọ ija ti o ti ku ni Ọgbẹni yi yio ma sọrọ rẹ kiri, o fi han gbangba pe *Akede Aiṣotọ* na ni nitotọ.

A dupẹ lọwọ awọn Olutọju Ijọ C.M.S. Ajido fun iranlọwọ igi Iwasu (*Pulpit*) ati Olukọni titun (*Teacher*) ti nwọn ṣẹṣẹ fi si Ajido, adura mi ni pe ki Ọlọrun ki o ṣe iranlọwọ fun nwọn.

Njẹ mo bere pe Ọgbẹni yi wa ninu imọran awọn Olutọju Ijọ C.M.S. Ajido bi? O da mi loju gbangba pe on ko si ninu awọn ẹniti o nro bi Ijọ C.M.S. Ajido yio ti ṣe lọ siwaju.

Lakotan, ko si ohun meji ti o ndun Ọgbẹni yi bikoṣe Ijọ Ọmọ Ibilẹ (*United African Methodist Church*) ti o de si Ajido ti awọn enia nla bi Ọgbẹni John Amusu (ti apele rẹ njẹ *Baptist*) ati Ọgbẹni Kiki Badiaran tẹwọgba, ti awọn enia bi Thomas Kiki ati Isaac Kunuji si jẹ Ọgagun ninu Ijọ Ọmọ Ibilẹ ti ko jẹ ki Ọgbẹni yi mọ ohun ti o dara fun ire ilu lati ma sọ.

Mo fẹ ki o ye Ọgbẹni yi pe, ti ko ba le e fun mi iru enia ti on jẹ ni Ajido, emi "Alọma vi" ki yio fi ọwọ mi ṣofo lati ma pa "era ti ko ni ọmọ ninu" mọ.

Temi ni lati wa ọna ti Ijọ Ọmọ Ibilẹ Ajido yio ti ṣe le bi agbo Oriṣa ti nwọn nsin ni Ajido ṣubu ki nwọn si yipada si Ọlọrun Ọga Ogo pẹlu Ododo ọkan nitori "Ododo ni o ngbe orilẹ ede leke" temi ki iṣe lati da ina ija silẹ larin ilu.

*Eko Akete* Ọwọ rẹ a roke, o ko ni tẹ o, ba ni sọ fun *Akede Aiṣotọ* yi ki o lọ so agbejẹ mọ idi rẹ ki o ma ba da si ara rẹ lọrun.

Bi Ọbẹni yi ba jẹ Ọmọ Ibilẹ Ajido o yẹ ki o ma wa ire ilu Ajido, ti o ba si nfẹ ire Ajido o ni lati ma dupẹ lọwọ Ọgbẹni ti o pe ni Woli ni ilu na, nitori Ọgbẹni na ni ẹniti gbogbo enia tabi Ọmọ Ibilẹ pataki ni Ajido mọ gbangba pe on li o mu iṣẹ rere ati alafia ati ilaju ti gbogbo awọn ara ilu na njẹ anfani rẹ loni yi ati gbogbo awọn ọmọ ilu Ajido ti o wa l' Eko ati ilu miran gbogbo ti nwọn si ndupẹ lọwọ Ọlọrun fun anfani yi, ti nwọn si nfi lati ma bọwọ fun Orukọ Ọgbẹni Ẹni nla yi.

"Ajanaku kuro ni mo ri nkan firi"
"Ẹgan ko ni ki Oyin ma dun"

*Eko Akete* ilu Eko yi yio dara, awọn enia miran ninu rẹ yio si ma yipada dapọ mọ " Ẹgbẹ Tunluṣe " alafia ati irẹpọ yio si ma bisi ni ilu Eko yi. *Aṣẹ.*

Ijọ Ọmọ Ibilẹ Ajido, Ẹ ma tẹsiwaju ninu iṣẹ rere gbogbo fun idagbasoke ilu wa Ajido. Aṣẹ

Emi ni tirẹ nitotọ,
" ALỌMA VI."


# Beer ! Beer ! Beer !

*We have just received a consignment of our celebrated* :—

" ELEPHANT " BRAND LAGER BEER.

*APPLY TO* :—

JOHN WALKDEN & CO., LTD.,
MARINA, LAGOS.

For price, etc.,


# Ero ya wa ra.

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo " Gbabiọgẹdẹ " nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣo loriṣiriṣi, Kọkọrọ ( Iṣika ) t'ilẹkun ati t'apoti loriṣiriṣi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda loriṣiriṣi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja loriṣiriṣi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun a ti Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, ( l'ebute Olowu ) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, ( l'Anikantamọ ) l'Eko.

O nta Iworo ( Golu ) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.


HOUSE TO LET.

A Storey-house at No. 13, Offin Road with a spacious yard containing two out-houses; the yard leading to four Streets: situate in a very good locality: suitable for business centre with all modern building equipments.

A Storey-house to suit everybody's taste.

For particulars, apply to the EDITOR.



LOOK HERE.

ALL READERS OF " EKO AKETE."

I. E. A. Olemọ of Iṣẹ Oluwa building 73, Ọdunfa Street (Anikantamọ) beg to inform the public that I now reopen my Workshop at the above address for Umbrella repairs.

Coloured Umbrellas, a speciality for our Kings, Princes and Chiefs.

Prices moderate

**A trial will convince you.**


B'O ṢOJU FẸRẸ, Ẹ F'ỌGA GBE !

Kẹkẹ Oku titun wa ni hihaya ni ile Ọgbẹni J. N. John, Alakoro, leti Sabu Ọgbẹni Doherty.

Kẹkẹ na jire, gere lo si ngbe oku sare lọ si Itẹ.

Ṣile mejila-abọ ni fun hihaya.

Ẹnyin ọmọ oloku abajalọrun a nreti nyin o.


# *Chairs ! Chairs ! ! Chairs ! ! !*

For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, ỌBUN-EKO STREET,
LAGOS.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m. Christ Church. | Bishop of Lagos (in Charge) |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30p.m. do. | do. |
| 9 a.m. St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | do. |
| 9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. St. David's (Jordan) | |
| 6.30 p.m. do. | |

**WESLAYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do | do. |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. T. D. Shaw |
| 7 p.m. | do. | Rev. Supd. G. A. Oke |
| 9 a.m. | Erelu | do. |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Laleye |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Meta) | Rev J. F. Ogunko |
| 6.30. p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinola |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 6 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji. |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Salem Church (Ebute Mẹta) | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. E. David Ṣodẹinde |
| 9. a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | Rev E. D. Ṣodẹinde |
| 3. p.m. | *(Confirmation Service)* | Rt. Rev. J. A. Lakẹru |

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. W. K. Faluwa |
| 4.30 p.m. | do. | Bro. E. A. Amosu |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. S. M. Phillips |
| 6 p.m. | | Bro. Joseph Adekọya |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. E. A. Ojo |
| 6.30 p.m. | Pastor Arinọla Ibarifo |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. | Resp'ble N. O. P. Ṣofoluwẹ |
| 7 p.m. | The Founder |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM.)**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.) |

**ZION CONGREGATIONAL.**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Rev. Supt. S. A. Coker. |
| 4 p.m. | do. | do. |

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Captain A. A. da Costa
7 p.m. do. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi :—

EKURỌ

£13 10 0—£14 fun *ton* kan

EPO.

£25 0 0 fun *ton* kan.

COCOA.

£18 0 0—£21 0 0 fun *ton* kan.

### KANO.

ẸPA.

£12 0 0 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.
Hides 5d fun lb kọkan.

ILE-ÒWÒ OYINBO ALALUMỌGAJI.

**John Holt**

NI ỌJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"

Keke-ologere (Elerin)

Keke-Ologere (*Rudge Whit-Worth*)

Panu Iborule

Awo

Awo-abomafo

Eja-abomafo

Iyefun

Sulfuri

Efun

Alum

Oda-dudu

Orisirisi Oda-ikunle

Iso

Panu-kiko'le

Isana (Atuko)

Ẹ bere ni Ṣabu **JOHN HOLT** ni, Opopo-nla, ni Eko.

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le lẹ si wọn nibikibi ni Eko tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

## "EMPIRE DAY" NI BADAGRY.

Si Oni'we-irohin "Eko-Akete."

Jọwọ fun mi ni aye diẹ lati fi esi si ọrọ "Akebioro" ti ọsẹ to kọja, totọ o le ro l'ọkan ara rẹ wipe a ko ri Bọkini kan ti o le ran Akọwe Ẹbun Adeniji lọwọ ninu eto ariya ti *Empire Day* ni Badagry, gẹgẹ bi o ti sọ sinu asọdnn rẹ: melo ni ninu awọn ọmọ Ibilẹ ti Akọwe yi pe lati ba ji roro ṣaju nipa ohun ti o tọ lati ṣe fun ti ọjọ *Empire* na, ti o si jẹ pe nwọn ti ba ṣe adehun lati ran lọwọ ṣugbọn nigbati akoko to a ko dẹ tun ri wọn mọ; eyi ki iṣe nkan iyani lẹnu rara. Awọn agba a ma p'owe bayi; Bo lonjẹ ri ẹ to roju, iwọ a dẹ fi aijẹ da a lara. Igbati Ẹbun Adeniji ko pe wa sibi eto ere rẹ gẹgẹ bi ọ ti pe nyin, bawo lo ti ro 'pe o yẹ fun wa lati wa ṣe atojubọ, bi ẹnyin ba nṣe bẹ, awa ki iṣe alatojubọ.

O dani loju gbangba pẹlu ẹri wipe ọpọlọpọ ọmọ Ibilẹ lo wa ni Badagry to nfẹ lati ṣe iranlọwọ sibi ere yi ṣugbọn a ko pe wọn.

Bẹni a ko le da ẹbi fun awọn Igbimọ ti ko wa ki nyin, ninu awọn Igbimọ ere ọjọ na a ko pe ninu wọn sibi Ijiroro ọrọ ere yi, ati ṣe ohun gbogbo tan ki a to sọ fun wọn. Eyi ha tọ bẹ? Bẹ ni enia ṣe? Totọ Badagry ni Oyinbo kọ de Orisun omi ki tobi, ọna na ti jin sẹhin diẹ o njẹ Ẹbun Adeniji lo ti nlani loju lat'ẹhin wa? Eyi ṣe kelebọ, ọkan ninu ọmọ Ibilẹ Badagry Arijoyọ a ko pe e sibi ere yi ṣugbọn o fi ifẹ wa fun ara rẹ, o si ba omidan Benka Coker jo a si fun ni "Ọrẹ Ijo ire," Iru awọn enia bawọnyi ko yẹ ki a fi oju pa wọn rẹ ninu ohunkohun.

Nipa akiyesi Afari-korodo eyi ki iṣe ọrọ ẹgan tabi abuku; aiye la ba iṣẹdalẹ yi, ki iṣe aṣa Badagry nikan leyi ṣugbọn aṣa ọpọlọpọ Ilu ni Ilẹ Yoruba Mo rope ẹniti o lo ede yi ko mọ Itumọ rẹ ki ba san fun u ko bere itumọ rẹ lọdọ awọn Agba na ko to lo iru ede yi ninu asọdun rẹ yi. Agbarigbabọ ohun ti a ba pe ni si on ni ama ṣe abojuto rẹ. Tani Ẹbun Adeniji?

Ṣugbọn awa dupẹ lọwọ Gollmer.

AGBADARIGI-BABA-OGUN.

---

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Jọwọ fun mi ni aye diẹ ninu Iwe-irohin rẹ.

Ki ọkunrin gbọ ki o wi fun obinrin, ki arale ti o gbọ wi fun ara idalẹ.

Ẹnikẹni ti o ba ni ohunkohun lati wi pẹlu mi tabi ti o fẹ lati ba mi sọ, ki o lọ ri *Lawyer* Akishemọnyin ni Breadfruit ni ilu Eko yi. Pẹlu ogo Oluwa ẹni na yio ri mi.

Emi SANDATU AṢAKẸ.




# ERVEN LUCAS BOLS

AMSTERDAM

**1575**

Whenever you see the word Bols it means a reputation of over 300 years.

***Bols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

## STONE JARS AND GLASS JARS

***5s.*** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

***DRINK IT NEAT.***

## H. S. Freeman

Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials

**Films, Post Cards, Views etc.; etc, on hand.**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic address* :—"**FREEDE**" **LAGOS.**

P. O. Box 495.

---

### ILE OWO KADUNA

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamo) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu işẹ yi, a[illegible]n ọja wa si to ọja o ni[illegible]igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi ti pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma gbe'ro: a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun şe ti a si tun nta lowo pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ẹniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe şọwọ si Olotu Ile-owo yi:—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

---

### ẸWA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemọh ti Ile Işẹ Oluwa ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) bẹrẹ işẹ agborun titun şe [illegible], baba rẹ nisisiyi. Ojo eşẹ ti iwọ ati Obinrin rẹ ma nsaba ju agborun yin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni kan mbẹ ni adugbo mi ti o mọ işẹ agborun nişişe lọpọlọpọ. Pọ lowo rẹ.




*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz:—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor:—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS:—Cash with Orders.

---

## AGA, AGA, AGA

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, ($1\frac{1}{2}$D.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,

Ọgbẹni J. A. OSHODI,

No. 26, ITA ỌBUN-Ẹ[illegible]

LI ẸKO.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

Per Case

**34s.**



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader*

has on hand Woollens in endless vari
at 50, Dosunmu Street, Lagos,

**Prices to suit everybody**

*Call now, fortune awaits you.*



## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe i
ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li
iku, ti Ounjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati E
iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa
ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti
ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Ọlọwọ—ag
Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi
fẹ ẹ ni *iọnu* a le ta a fun o, Iṣana Alapoti fun
ko si bi a ti nṣe wọn. Orişirişi ọja lo wa
wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere
nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa
rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "K
ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ j
wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọk
2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin
kowe ṣọwọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba s

E. O. AMBẸ & BRO
38, Moloney Bridge Street,
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangal*
Idumagbo, Eko.



## Ile Ita Egbogi ti Macaulay

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orişirişi Egbogi lo ṣẹṣẹ de
wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriş
ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Ar
ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, c
Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a k
mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si j
idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo
ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED B
ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.